# NIGBA TI A MU ỌGBÀ KURO

**Jobu 1:1-22; 2:1-10; 13:15; 23:1-17; 27:1-6; 42:1-17**

**ẸKỌ 372 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “OLUWA fifunni OLUWA si gbà lọ, ibukun li orukọ OLUWA” (Jobu 1:21).**

## Ọta Wa

Satani ni ọta wa. O le maa rin kaa kiri “bi kiniun ti nke ramuramu, … o nwá ẹniti yio pajẹ kiri” (1 Peteru 5:8). O le pa ara rẹ̀ dà di “angẹli imọlẹ” lati gbiyanju lati tan awọn eniyan jẹ (2 Kọrinti 11:14). Gbogbo igba ni o maa n ri iṣẹ ṣe. Ni ọna kan tabi omiran, o n du u lati já wa kuro lọdọ Oluwa. Ki i ṣe pe o gbọ́n nikan, ṣugbọn o kun fun ẹ̀tan pẹlu.

Igba pupọ ni Satani maa n lo ọgbọn ẹ̀wẹ ti awọn eniyan mọ ni ori-yiya. Oun a kó oriṣiriṣi èrokérò ati ètekéte sinu agbari awọn eniyan. Satani maa n mu ki awọn eniyan kan maa ba awọn ẹlomiran jiyan titi wọn o fi gba eke gbọ́. Ṣugbọn a gbọdọ ranti pe “eke ni” Satani “ati baba eke” (Johannu 8:44).

Satani gboya to bẹẹ ti o fi dán Ọmọ Ọlọrun paapaa wo. Lẹyin ti Jesu ti gbadura ti O si ti gbaawẹ̀ fun ogoji ọjọ ninu iju, Satani gbidanwo lati mu Un ki O gbọ́ ti oun. Jesu lo ọ̀rọ inu Iwe Mimọ́ bi ohun ija lati da a lohun. Satani paapaa lo ọ̀rọ lati inu Iwe Mimọ́, ṣugbọn ọna ti o lodi ni o gbà lo o. Otitọ ọ̀rọ ti eniyan sọ lọna odi buru bakan naa gẹgẹ bi eke ti buru. Awọn ileri Ọlọrun jẹ itunu iyebiye, ṣugbọn a gbọdọ lo wọn ni ọna ti Oun fẹ ki a lo wọn.

Jesu kò fi ara silẹ fun idanwo Satani. Bẹẹ ni awa naa kò ni lati fi ara silẹ fun idanwo. Olododo ni Ọlọrun si wa ki yoo si jẹ ki a dán wa wò ju bi awa ti le gbà, ati pẹlu ninu idanwo naa Oluwa yoo si ṣe ọ̀na ati yọ ninu rẹ̀ (1 Kọrinti 10:13).

Olukuluku ni lati maa reti idanwo. Jesu, Ẹni ti kò da ẹ̀ṣẹkẹṣẹ, a dan An wò ṣugbọn kò fi ara silẹ. Apẹẹrẹ ẹlomiran ti o fara da idanwo ni Jobu. O ni ọrọ̀ pupọ to bẹẹ ti o fi “pọ̀ jù gbogbo awọn ọmọ ara ila-õrùn lọ.” Oun a maa dide ni kutukutu owurọ lati sin Ọlọrun. O maa n gbadura fun awọn ọmọ rẹ̀, o si maa n rubọ si Ọlọrun nigba gbogbo nitori wọn. Jobu jẹ ẹniti “o pé,” o bẹ̀ru Ọlọrun, o si korira ibi; sibẹ̀ a dán an wò.

## Ninu Ile-isin

Ni ọjọ kan nigba ti awọn eniyan kó ara wọn jọ siwaju Oluwa -gẹgẹ bi igba ti awa naa ba lọ si ile-isin – Satani paapaa wá, ṣugbọn ki i ṣe fun rere. Bakan naa ni o si maa n wá si ile-isin. O maa n lo awọn ọmọde ati awọn ọ̀dọ́ lati maa ji ọ̀rọ sọ, lati maa fi iwe orin ṣire, tabi lati maa kọ iwe to bẹẹ ti wọn fi maa n di awọn ẹlomiran lọwọ, awọn tikalara wọn a si padanu ire ti wọn i ba gbà ninu ipade naa. Nigba miiran Satani a fi oorun kun awọn eniyan ninu ile-isin, tabi ki o rán wọn leti nnkan miiran eyi ti kò ni jẹ ki wọn gbọ́ ohun ti alufaa n sọ. Nigba ti a ba si pe awọn eniyan lati wá si ori pẹpẹ, Satani a sọ fun wọn pe o ṣanfaani ki wọn maa lọ si ile, nitori pe ilẹ ti ṣú, tabi pe wọn le gbadura ni igba miiran ati ni ibikibi. Ẹ jẹ ki a kiyesara nigba ti a ba lọ si ile-isin bibẹẹkọ Satani yoo tàn wá jẹ.

## Ibeere

Oluwa si bi Satani leere ibi ti o ti wá. Satani si dahun pe lati “ilọ siwá sẹhin lori ilẹ aiye, ati ni irinkerindo ninu rẹ̀.” Ọwọ́ rẹ̀ ti kun fun iṣẹ, nipa wiwá ibi lati ṣe. Lai si aniani otitọ ni o sọ. Nigba miiran Satani a maa sọ otitọ, lati da awọn eniyan ni ède rú. Ki ni idahun rẹ yoo jẹ, ni ọjọ kan nigba ti o lọ si ile-isin bi Oluwa ba beere wi pe ki ni o ti n ṣe? Iwọ o ha le jẹwọ pe n ṣe ni o ti n yọ aburo rẹ ọkunrin kekere lẹnu, pe o ti ṣe aigbọran si awọn obi rẹ, tabi pe o ti huwa aigbọran ni ile-ẹ̀kọ́? Tabi iwọ o ha le dahun pe o ti fi Jesu hàn ninu igbesi-ayé rẹ ati pe o ti jẹ ki imọlẹ rẹ ki o mọlẹ, ati pe o ti ṣe ọmọ rere ati oluranlọwọ fun awọn ẹlomiran?

**Ọgbà**

Oluwa ati Satani kiyesi Jobu, ọkunrin ti o n sin Ọlọrun. Satani dahun, "Jobu ha bẹ̀ru Oluwa li asan bi?" O sọ fun Ọlọrun pe ọgbà wà yí Jobu ká -- ọgbà aabo Ọlọrun. Satani sun Jobu lẹsun pe Jobu ki yoo jẹ́ oloootọ si Ọlọrun bi a ba mú ọgbà nì kuro. Lati fi hàn pe Satani ṣe èké, Ọlọrun mú ọgbà naa kuro ṣugbọn kò gba Satani láyè lati "fi ọwọ́ kan" Jobu tikara rẹ̀. Lai si aniani, Oluwa fi àye eyi silẹ lati fi han Satani, Jobu ati awa pẹlu pe Ọlọrun yoo pa ẹnikẹni ti ó wà labẹ idanwo kikoro mọ́.

**Adanu**

Ọna ti Satani gbà fi bà Jobu jà ni eyi. Ni ọjọ kan iranṣẹ kan tọ Jobu wa o si wi pe awọn ọ̀tá ara Saba kó ẹẹdẹgbẹta ọdá-malu, ati ẹẹdẹgbẹta kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ lọ. Wọn si ti pa awọn iranṣẹ rẹ̀ bi ko ṣe oun nikan ṣoṣo ti o wá sọ fun un ni o sá là. Ki iranṣẹ nì to pari iroyin rẹ̀ ọkan ninu awọn oluṣọ-agutan wọle de. Iroyin tirẹ̀ ni lati sọ fun Jobu pe gbogbo awọn agutan rẹ̀ --ẹẹdẹgbaarin ati awọn ti n tọju wọn ni o ti kú, oun nikan ṣoṣo ti o wá fun un ni iroyin ni o yè. Iranṣẹ miiran tun de pẹlu iroyin pe gbogbo ẹgbẹẹdogun ibakasiẹ Jobu ni awọn ara Kaldea ti kó lọ, pẹlupẹlu wọn si fi ida pa awọn olutọju wọn. Oun nikan ṣoṣo ni o sá là. Bẹẹ ni ẹlomiran ninu awọn oṣiṣẹ rẹ̀ tun dé ti o sọ fun Jobu pe awọn ọmọkunrin rẹ̀ mejeeje ati awọn ọmọbinrin rẹ̀ mẹtẹẹta ni o ti kú ninu iji ti o jà. Wo adanu kan lori ekeji! Wo iru ipaya ti yoo bá Jobu! Wo bi ibanujẹ Jobu yoo ti pọ to!

**Jijẹ Oloootọ**

Ọpọlọpọ eniyan ni o ti ni iriri pipa adanu ati kikọja ninu idanwo; ṣugbọn a ha ti i yiri ẹnikini wò to ti Jobu? Ki ni Jobu ṣe labẹ iyiriwo kikoro bẹẹ? Gẹgẹ bi aṣa, lati fi ibanujẹ rẹ̀ hàn, Jobu "fa aṣọ igunwa rẹ̀ ya, o si fari rẹ̀, o wolẹ" – o si gbadura si Ọlọrun. Lai si aniani, ẹnu ya Satani. O ti sọ pe Jobu yoo bú Ọlọrun. Irọ́ ni Satani pa a si bori rẹ̀ nigba ti Jobu yin Ọlọrun logo. Jobu mọ pe Ọlọrun ni o fun oun ni gbogbo ọrọ̀ ati ibukun ti oun ni. Pẹlupẹlu o tun mọ pe oun kò le kó wọn lọ nigba ti oun ba kú. O mọ pe iriju ni oun jẹ́ lati boju to awọn nnkan wọnyii niwọn igba ti Ọlọrun ba fẹ bẹẹ.

**Agbara ti o Lopin**

Ọlọrun rán Satani leti pe Jobu jẹ́ oloootọ laaarin idanwo rẹ̀. Jobu jẹ́ ẹni "pipe" sibẹ. Bi o tilẹ ṣe pe Satani gbidanwo "lati run u lainidi" o si ti dán an wò lati ba irẹpọ rẹ̀ pẹlu Ọlọrun jẹ, Jobu di igbagbọ́ rẹ̀ mu ṣinṣin. Nigba naa ni Satani tun sọ pe ọran ki ba ti ri bẹẹ bi o ba ṣe pe Jobu mọ pe oun yoo kú. Satani wi pe, "Ohun gbogbo ti enia ni, on ni yio fi rà ẹmi rẹ̀." Eyini le jẹ otitọ nipa awọn ẹlomiran, paapaa awọn ti kò ni igbala. Ẹru maa n ba wọn lati lọ fi oju kan Ọlọrun. Ẹ jẹ ki a wo ohun ti o ṣẹlẹ si Jobu.

Ọlọrun gbà fun Satani lati yiiri Jobu wò ṣugbọn ki o dá ẹmi rẹ̀ si. Agbara Satani lopin. Bi o tilẹ jẹ pe o lagbara pupọ, Ọlọrun lagbara ju u lọ. Nigba ti Ọlọrun ba ti fi aala lelẹ, Satani kò le kọja rẹ̀.

**Oówo**

Satani pọ́n Jobu loju. Oowo bò o, eyi ni lati ṣe eniyan laanu lati wò. Iyawo rẹ̀ ri iru ipo oṣi ti o wà. O sọ fun un pe o yẹ ki o bú Ọlọrun ki o si kú -- bi ẹni pe kò si ireti kankan mọ́ nipa ti ara ati nipa ti ẹmi, fun Jobu. Ṣugbọn Jobu kò jẹ dẹṣẹ nipa titẹ le imọran rẹ̀. Jobu sọ ohun ti ó wà ninu ọkàn rẹ̀. O ni, "Kinla! awa o ha gba ire lọwọ Ọlọrun, ki a má si gba ibi?"

**Awọn Ọrẹ Mẹta**

Mẹta ninu awọn ọ̀rẹ́ Jobu wá lati tu u ninu. Fun ọjọ meje tọsan toru ni wọn fi joko ti Jobu ti wọn sa n wo o. Kò si ọkan ninu wọn ti o dá ọ̀rọ kan sọ. Boya eyi paapaa tun jẹ iyiriwo kan yatọ si irora oowo rẹ̀. Wọn kò fun Jobu ni "itunu" kan rara. Awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ mẹta ti di ẹni ifisọ̀rọ sọ ni aye. "Awọn olutunu Jobu" ni awọn wọnni ti n fini sùn dipo ki wọn jẹ abánikẹ́dùn.

**Iranwọ Kò Si lati ọdọ Awọn Ọrẹ Rẹ̀**

Jobu ṣe aroye o si fẹ pe ki oun kú. Njẹ oowo ti sọ ọ ri? Boya oye diẹ le ye ọ nipa bi irora rẹ̀ ti pọ to nigba ti oówo sọ ọ lati atẹlẹsẹ titi de atari. Bi o tilẹ jẹ pe Jobu wà ninu irora ati ibanujẹ, o di igbagbọ́ ati ireti rẹ̀ ninu Ọlọrun mu. O ni, "Bi o (Ọlọrun) tilẹ pa mi, sibẹ emi o ma gbẹkẹle e."

Awọn ọ̀rẹ́ Jobu kò jẹ iranwọ kankan fun un. Jobu fi ye wọn pe bi o ba ṣe pe awọn ni igba yí pada fun bẹẹ, oun i ba du u lati ṣe iranwọ ati lati mu wọn ni ọkàn le. Eyi ni i ba si jẹ pipa Ofin Wura nì mọ́: “Nitorina gbogbo ohunkohun ti ẹnyin ba nfẹ ki enia ki o ṣe si nyin, bẽni ki ẹnyin ki o si ṣe si wọn gẹgẹ” (Matteu 7:12).

**Lailẹṣẹ**

Jobu kọ ẹ̀sùn ti awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ fi sun un pe n ṣe ni o ti dá ẹ̀ṣẹ. O mọ pe ọkàn rẹ̀ ṣe deedee niwaju Ọlọrun. Bi o tilẹ jẹ pe a dan an wò titi de ogogóró nipa ibanujẹ̀, nipa irora ati nipa ọ̀rọ awọn “olutunu” rẹ̀, Jobu pinnu lati di ododo rẹ̀ mú sibẹ. O jẹ ifẹ ọkàn Jobu pe ki oun le duro niwaju Ọlọrun nitori pe Oluwa mọ otitọ ti iyiriwo yii. Jobu mọ pe iyiriwo ni, ati pe Ọlọrun fẹ́ bẹẹ ni.

Awọn miiran maa n ro pe ibanujẹ, aisan, ati wahala maa n wá gẹgẹ bi idajọ fun ẹ̀ṣẹ nikan ni. Ki i ṣe igba gbogbo ni o maa n jẹ bẹẹ. Peteru kọ iwe si awọn Onigbagbọ́: “Olufẹ, ẹ máṣe ka idanwò iná ti mbẹ larin nyin eyiti o de si nyin lati dan nyin wò bi ẹnipe ohun àjeji li o de bá nyin: ṣugbọn niwọnbi ẹnyin ti jẹ alabapin iya Kristi, ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o le yọ̀ ayọ̀ pipọ nigbati a ba fi ogo rẹ̀ hàn” (1 Peteru 4:12, 13). Ni ọjọ kan nigba ti Jesu pade ọkunrin afọju kan, wọn bi I lere ẹni ti o dẹ̀ṣẹ, ọkunrin naa ni tabi awọn obi rẹ̀. Jesu si dahun pe ki i ṣe pe nitori ti ẹnikẹni ninu wọn dá ẹ̀ṣẹ ṣugbọn ọkunrin naa fọju, ki a le fi ogo Ọlọrun hàn ni. A la ọkunrin naa ni oju o si fi ogo fun Jesu.

**Aijọgọ Silẹ Ninu Idanwo**

Ẹri Jobu ni pe oun ti rin ni ọ̀na Oluwa, oun ti pa ofin Rẹ̀ mọ́, ati pe oun ka Ọrọ Ọlọrun si ohun danindanin ju ounjẹ fun inu oun. Jobu ni: “Ṣugbọn on (Ọlọrun) mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura.” Wo bi yoo ti jẹ́ ohun iyanu to bi ẹni kọọkan wa ba ni ipinnu lati kọja ninu idanwo pẹlu iru iṣẹgun bẹẹ! Jobu la idanwo yii kọja lai fi ara fun un. Bi Jobu ti n ṣe aṣaro lori titobi Ọlọrun ati agbara Rẹ̀, o mọ bi eniyan ti jẹ alainilaari to. O tun wa dun Jobu pe oun tilẹ ṣe àroye rara. Jobu fi rere san ibi. O gbadura fun awọn ọrẹ rẹ̀ mẹta ti wọn kò sọ otitọ.

Ọlọrun bukun fun Jobu O si fun un ni ilọpo meji gbogbo ohun ti o ti ni tẹlẹ ri to bẹẹ ti igbẹyin ayé Jobu fi jẹ eyi ti o dara ju lọ ninu igbesi-ayé rẹ̀. Njẹ iwọ ro pe o pé fun Jobu lati jẹ́ oloootọ si Ọlọrun?

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti a ka Jobu si ẹni ti o “pọ̀ jù gbogbo awọn ọmọ ara ila-õrùn lọ?”

2 Ta ni lọ si ile-isin lati lọ ṣe idiwọ dipo ki o lọ jọsin?

3 Ki ni Oluwa fi yi Jobu ká lati pa a mọ?

4 Ki ni Satani ṣe nigba ti a mu ọgbà naa kuro?

5 Ki ni Jobu ṣe nigba ti o padanu ohun gbogbo?

6 Ki ni a fi hàn nigba ti Jobu kò ṣe gẹgẹ bi Satani ti sọ?

7 Ọna wo ni Satani gba pọ́n Jobu loju?

8 Ki ni ṣe ti awọn ọrẹ Jobu wá?

9 Bawo ni Jobu ṣe la idanwo rẹ̀ já?

10 Ki ni Ọlọrun ṣe fun Jobu lẹyin idanwo yii?